Awọn malaika o nii maa bẹ pẹlu ikọ kan ti aja ati agogo ba wa pẹlu wọn

Lati ọdọ Abu Huraira- ki Ọlọhun yọnu si i- dajudaju ojiṣẹ Ọlọhun- ki ikẹ Ọlọhun ati ọla Rẹ maa ba a- sọ pé: «Awọn malaika o nii maa bẹ pẹlu ikọ kan ti aja ati agogo ba wa pẹlu wọn ».

[O ni alaafia] [Muslim gba a wa]

Anabi - ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a - funni niroo pe dajudaju awọn malaika o nii wa pẹlu ikọ arin irin-ajo kan ti aja n bẹ pẹlu wọn, tabi agogo ti wọn maa n gbe kọ ọrun awọn ẹranko ti wọn maa n gùn ti yio maa mu ohun wa ti o ba ti n lọ.

http://sunnah.global/hadeeth/yo/show/8951